Ẹ́kísódù 3 sí 12

Fi àyọkà kọ̀ọ̀kan tó wà nísàlẹ̀ yíí wéra pẹ̀lú àwọn àwòrán tó wà lápá ọ̀tún kó o lè mọ ẹni tó sọ ọ̀rọ̀ náà.

1.

"ÈMI YÓÒ JẸ́ OHUN TÍ ÈMI YÓÒ JẸ́."
—ẸKÍSÓDÙ 3:14.

2.

"ẸNU MI WÚWO, AHỌ̀N MI SÌ WÚWO."
—ẸKÍSÓDÙ 4:10.

3.

"TA NI JÈHÓFÀ, TÍ ÈMI YÓÒ FI ṢÈGBỌRÀN SÍ OHÙN RẸ̀ LÁTI RÁN ÍSÍRẸ̀LÌ LỌ?"
—ẸKÍSÓDÙ 5:2.

4.

"ÌKA ỌLỌ́RUN NI ÈYÍ!"
—ẸKÍSÓDÙ 8:19.



A. Àwọn àlùfáà pidánpidán

B. Jèhófà Ọlọ́run

D. Mósè

E. Fáráò

▶ **GBÌYÀNJÚ ÈYÍ WÒ:** Kọ́ nípa ìdí tí Ọlọ́run fi ń jẹ́ Jèhófà. Wọ́n gbé Mósè ọmọ jòjòló jáde látinú Odò Náílì, ìtumọ̀ orúkọ rẹ̀ ni "Fà Jáde," tàbí "Tá A Gbà Là Látinú Omi," lédè Hébérù. Àmọ́ kí nìdí tí Ọlọ́run fi fún ara rẹ̀ lórúkọ tí wọ́n ń pè ní Jèhófà lédè Hébérù? Lo *ÀKÁ ÌWÉ ORÍ ÍŃTÁNẸ́ẸTÌ ti Watchtower* lórí ìkànnì www.jw.org/yo (wo abẹ́ ÀWỌN ÌTẸ̀JÁDE > ÀKÁ ÌWÉ ORÍ ÍŃTÁNẸ́ẸTÌ) tàbí àwọn ohun ìwádií míì tó o ní láti fi wá ìdáhùn. Kí nìdí tó o fi rò pé Jèhófà ni orúkọ tó yẹ ká máa pe Ọlọ́run?

Ìdáhùn: 1. B. 2. D. 3. E. 4. A.

www.jw.org/yo © 2014 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania